“Adamọ marun-un lo jẹ: Dida abẹ ati fifa irun abẹ ati gige tubọmu ati gige awọn èékánná ati fifa irun abiya”

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Mo gbọ́ ti Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe: “Adamọ marun-un lo jẹ: Dida abẹ ati fifa irun abẹ ati gige tubọmu ati gige awọn èékánná ati fifa irun abiya”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé pe awọn iwa marun-un kan n bẹ ninu ẹsin Isilaamu ati ninu sunnah awọn ojiṣẹ: Akọkọ nibẹ ni: Dida abẹ, oun ni gige awọ ti o lekun lori nnkan ọmọkunrin lori adenderi, ati gige ori awọ ti o wa lori oju ara obinrin lori aye ibi ti nnkan ọmọkunrin maa n wọle si. Ikeji nibẹ ni: Fifa irun abẹ, oun ni irun oju ara ti o wa ni àyíká oju ara. Ikẹta nibẹ ni: Gige tubọmu, oun ni gige nnkan ti o hù jade lori ete ọkunrin oke nibi ti ete ti maa hàn. Ikẹrin nibẹ ni: Gige awọn èékánná. Ikarun-un nibẹ ni: Gige irun abiya.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3144